**JOINT UNIVERSITIES PRELIMINARY EXAMINATIONS BOARD (JUPEB)**
**2015 EXAMINATIONS**
**YORUBA – ART –J129**

**MULTIPLE CHOICE QUESTIONS**

1. **Ònìṣà** jẹ́ ọ̀rọ̀ tí a yá lò láti inú èdè wo?
   A. Haúsá
   B. Ìgbò
   C. Faransé
   D. Lárúbáwá

2. Àwọn àmì-ohùn wo ni a fi pe **ALUFAA**
   A. Ìsàlẹ̀ Ìsàlẹ̀ òkè ìsàlẹ̀
   B. Òkè òkè ìsàlẹ̀ ìsàlẹ̀
   C. Ààrin ààrin òkè òkè
   D. Òkè Ìsàlẹ̀ Àràrin oke

3. Àwọn ìró fáwẹ́lì àyanudíẹ̀pè ni
   A. e ẹ ọ an
   B. e o ẹ ọ
   C. ẹ ọ ẹn ọn
   D. i u e o

4. Bátànì sílébù inú**AṢENIBÁNIDÁRÒ** ni
   A. FK-KF-KF-N-KF-KF
   B. F-KF-KF-KF-KF-KF-KF
   C. KF-N-KF-KF-N-KF-KF
   D. F-KF-KF-KF-KF-KF

5. Èwo ni àpẹẹrẹ àyálò ọ̀rọ̀ láti inú èdè Lárùbáwá?
   A. Ṣinmí
   B. Káàdì
   C. Àlùfáà
   D Dafidi

6. Ìró ohùn ẹlẹ́yọ̀ọ̀rodò ni
   A. [v]
   B. [/]
   C. [^]
   D. [\]

7. Àpẹẹrẹ àrànmọ́ afòró ni
   A. kúulé
   B. tanmóko
   C. ẹlẹ́gàn
   D. àgbọ́ọ̀dá

8. Èwo ni àmì fóònù nínú àwọn wọ̀nyí?
   A. //
   B. ^
   C. v
   D. [ ]

9. Da ìró **ẹ** kọ ní ìlànà fónẹ́tíìkì.
   A. [ɛ]
   B. [ɔ]
   C. [ɛ̣]
   D. [ɜ]

10. Kọ ọ̀rọ̀ yìí, **Jẹ́ñyọ̀** sílẹ̀ ní ìlànà fónẹ́tíìkì.
    A. [ʤɛ́ñjɔ̀]
    B. [jẹ́ñjɔ̀]
    C. [dɛ́yọ]
    D. [gbẹ̀ǹyọ̀]

11. Èwo ni ìró kọ́ńsónáǹtì àfúnnupè nínú àwọn wọ̀nyí?
    A. s
    B. m
    C. r
    D. w

12. Ìró kọ́ńsónáǹtì àránmúpè méjì ti èdè Yorùbá ni –
    A. r àti s
    B. kp àti gb
    C. m àti n
    D. ṣ àti s

13. Èwo nínú àwọn wọ̀nyí ni ìyísódì abèjì?

    A. Kò tí ì lọ.

    B. Ọ̀rẹ́ mi kọ́ ni ó kú.

    C. Kì í ṣe èmi ni ò lọ.

    D. Kì í ṣe èmi ni ó lọ.

14. Irú ọ̀rọ̀-ìṣe wo ni ó jẹyọ nínú: ‘**Yétúndé ra ẹja dín tà**.’?

A. àsínpọ̀

B. ẹlẹ́là

C. aláìlẹ́là

D. gíríkì

15. *fíofío* jẹyọ nípa àpètúnpè ------- nínú **igi náà ga fíofío**

A. afiyehàn

B. afitẹnumọ́hàn

C. afolùṣehàn

D. afiṣehàn

16. Ọ̀nà tí a gbà ṣẹ̀dá **ilé-ìwé** ni

A. lílo àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe

B. lílo àfòmọ́-ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ

C. ṣíṣe àpapọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe méjì

D. ṣíṣe àpapọ̀ ọ̀rọ̀-orúkọ méjì

17. Àpẹẹrẹ àpètúnpè kíkún ni

A. ọ̀sẹ̀ẹ̀sẹ̀

B. ọ̀sẹ̀ọ̀sẹ̀

C. ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀

D. ọ̀sẹ̀sẹ̀

18. Tọka sí ọ̀rọ̀ àpètúnpè ayísọ̀rípadà nínú ìwọ̀nyí:

A. dáradára

B. ọmọọmọ

C. tónítóní

D. yékéyéké

19. Àpẹẹrẹ gbólóhùn àṣẹ tààrà ni

A. Tọ́ ayé wò.

B. Kí a máa lọ.

C. Pé kí o wá.

D. Mo fẹ́ kí a gbàdúrà.

20. A ṣẹ̀dá **òǹrorò** nípa lílo àfòmọ́:

A. àárín

B. ìbẹ̀rẹ̀

C. ìparí

D. òkè

21. ‘**Adé á ti máa kọrin,’ ti** nínú gbólóhùn yìí jẹ́ àpẹẹrẹ ----------

A. Àìṣetán atẹ́rẹrẹ

B. Àìṣetán bárakú

C. Àṣetán ìbẹ̀rẹ̀

D. Gbòógì

22. Àpólà wo ni a fàlà sí nínú gbólóhùn **Adé <u>mu ẹmu ògidì ní Ìlá</u>.**?

A. Àpólà ìṣe

B. Àpólà orúkọ

C. Àpólà atọ́kùn

D. Àpólà àpọ́nlé

23. ***Ìwé*** jẹ́ àbọ̀ fún ọ̀rọ̀ wo nínú gbólóhùn yìí: ‘**Akẹ́kọ̀ọ́ fẹ́ràn eré ju ìwé kíkà lọ.**’?

A. Ọ̀rọ̀-atókùn

B. Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé

C. Ọ̀rọ̀-àpèjúwe

D. Ọ̀rọ̀-ìṣe

24. Èwo ni atọ́ka awẹ́ gbólóhùn aṣàpèjúwe?

A. ni

B. sí

C. ó

D tí

25. Tọ́ka sí àpólà atọ́kùn nínú **Délé sọ ọ̀rọ̀ tirẹ̀ ní ṣókí.**

A. Délé sọ

B. Sọ ọ̀rọ̀

C. Ọ̀rọ̀ tirẹ̀

D. Ní ṣókí

26. Lítírésọ̀ dá lórí ìbáṣepọ̀ àti ìhùwàsí láàrin --------

A. Èniyàn

B. Ẹranko

C. Kòkòrò

D. Ewéko

27. Láàárín àwọn wo ni alámọ̀ ti wọ́pọ̀ jù?
    A. Ìbàràpá
    B. ìbàdàn
    C. Èkìtì
    D. Ìjẹ̀sà

28. Orin tí ó wà nínú àlọ́-onítàn ni ó jẹ́ kí a máa pè é ní --------
    A. Àlọ àpamọ̀
    B. alọ onítàn
    C. àlọ́ apagbè
    D. àló lásán

29. Ọdún ìbálẹ̀ kọ̀ọ̀kan lo máa ń ní ---------
    A. ewu
    B. ọjọ́
    C. ìrí
    D. ìlú

30. Rárà jẹ́ ìsàré tí a máa ń fi ki ènìyàn níbi ayẹyẹ láàrin àwọn ------------
    A. Ọ̀yọ́
    B. Ẹ̀gbá
    C. Ìjẹ̀bú
    D. Ọ̀wọ̀

31. Asunrárà kì í ----------------
    A. Dìtẹ̀
    B. Bẹ̀rù
    C. Jọba
    D. Ṣèké

32. Awọn ọ̀rọ̀ wo ni o maa n wọ́pọ̀ nínú rárà?

A. Ọ̀rọ̀ àbámọ̀

B. Ọ̀rọ̀ àṣẹ

C. Ọ̀rọ̀ ọgbọ́n

D. Ọ̀rọ̀ òdì

33. Rárà àwọn ayaba ni

A. Ẹ̀kún ìyàwó

B. Rárà

C. Ìjálá

D. Yùngbà

34. Kín ni alubàtá kì í ṣe?

A. Kì í dákú

B. B. Kì í dájọ́

C. Kì í dárin

D. Kì í dáṣọ

35. Àwọn wo ni a máa ń kọ orin ìrẹmọ fún?

A. Onílù

B. Ìkókó

C. Egúngún

D. Òrìṣà

36. Irú bátàni wo lo wọ́pọ̀ nínú orin eré ìdárayá?

A. gbígbè

B. lílé àti gbígbé

C. lílé

D. orin

37. Orin òrìṣà wo ni à ń kọ ní Ilé-ifẹ̀?

A. Ògògó

B. edì

C. ayẹyẹ

D. ìgbàlà

38. Kín ni iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá?

A. Ìpèsè

B. Ìṣọ̀tẹ̀

C. Ìkìlọ̀

D. Ìdúpẹ́

39. Òǹkọ̀wé gbọ́dọ̀ ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn mìíràn tí yóò ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú -----------

A. ẹ̀dá-ìtàn kékeré

B. olú ẹ̀dá-ìtàn

C. ẹ̀dá-ìtàn ọkùnrin

D. ẹ̀dá-ìtàn obìnrin

40. Òǹkọ̀wé ń ṣẹ̀dá ẹ̀dá-ìtàn kọ̀ọ̀kan láti fi ----------

A. jọba

B. jíṣẹ́

C. járọ́

D. járọ̀

41. Kín ló máa ń wáyé ní ibùdó-ìtàn?

A. ìrírí

B. ìtàkurọ̀sọ

C. ìṣẹ̀lẹ̀

D. awuyewuye

42. Kín ni irinṣẹ́ tó ṣe pàtàkì jù lọ fún oníṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀?

A. ọ̀rọ̀

B. àpólà

C. gbólóhùn

D. èdè

43. Orúkọ àjùmọ́jẹ kan tí a fi ké tàbí kà ewì ni ------------

A. ọ̀rọ̀

B. ètò

C. ohùn

D. orin

44. Èdè-ewì jẹ́ irúfẹ́ èdè -------------------

A. tútù

B. líle

C. gbẹ̀fẹ́

D. gbígbẹ

45. Kín ni akéwì gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ ní lọ́kàn kí ó tó kọ ewì?

A. ibùdó-ìtàn

B. ẹ̀dá-tàn

C. kókó-ọ̀rọ̀

D. agbo ìṣèré

46. Ìtàn tí òǹkọ̀wé fi inú rò, tó kọ sílẹ̀ fún ìgbádùn àwọn òǹkàwé ni ----------

A. ìtàn-àròsọ

B. ìtàn òǹkọ̀wé

C. ìtàn ìwásẹ̀

D. ìtàn orírun

47. Ọ̀kan lára oríṣìí ìtàn-àròsọ tó wà ni ------------

A. méríìírí

B. àgbélẹ̀rọ

C. asọ̀gbà

D. apààlà

48. Àkòrí orí kìíní nínú ìwé <u>Ìrèké Oníbùdó</u> ni -------------

A. Ìlú àlùpàyídà
B. Ìtánforítì
C. Pípàdé àwọn abàmì ẹ̀dá
D. Ìrèké Oníbùdó

49. Dípò ọkùnrin rúgúdú, ta ni Ìrèké Oníbùdó tún rí lọ́nà oko bàbá rẹ̀?

A. wèrè

B. arẹwà obìnrin

C. ọkùnrin alákìísà kan

D. oníṣòwò

50. Ìmọ̀ràn Ìrèké Oníbùdó fún ẹni tí a fi ìyà jẹ ní òde ayé ni pé kí á ----------

A. gbẹ̀san

B. ní sùúru

C. ronú dáadáa fún ìgbọ̀nyànù

D. fa ìbínú yọ

## YORÚBÁ ESSAY QUESTIONS

### YOR 001: Language I: Yorúbá Phonology

1. Jíròrò lórí àǹkóò àtí ìjẹyọpọ̀ fáwẹ́lì èdè Yorúbá. (15 marks)
2. Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí sílébù èdè Yorùbá. (15 marks)

### YOR 002: Language II: Yorúbá Grammar

3. Fi ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ ṣàlàyé àtúnpín ìsọrí ọ̀rọ̀-orúkọ lédè Yorùbá? (15 marks)
4. Jíròrò lórí ọ̀rọ̀-arọ́pò orúkọ lédè Yorùbá. (15 marks)

### YOR 003: Literature I: Yorúbá Oral Literature

5. Kọ àpẹẹrẹ orin "ẹkún ìyàwó" kan tí o mọ̀. Kí o sì ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀. (15 marks)
6. Pààlà láàrin lítíréṣọ̀ alóhùn àti lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. (15 marks)

### YOR 004: Literature II: Written Yorúbá Literature

7. Ṣe àlàyé ipa pàtàkì tí àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá Yorùbá ń kó láwùjọ. (15 marks)
8. Ojú wo ni Ìṣọ̀lá fi wo *Òrìṣa* tó ń gun àwọn Òǹkọ̀wé? (15 marks)